The Chief Secretary to the Government

Mr. Herbert Macaulay's Open Letter to the Governor (Yoruba Version).


SPECIAL EDITION.

# EKO AKETE.

"Emi vio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. V. No 255. SATURDAY, DECEMBER 31, 1927. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

5 JAN 1928

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi ṣilẹ.

"AWA O MA JO, AWA O MA YỌ, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

Office :—
No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

# Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKẸ Oniṣowo "Gbabiọgẹdọ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọṣan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-ṣawa okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ṣọbu rẹ No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute lowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge treet, (l'Anikantamọ) l'Eko.

**Ọ nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati in-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.**

**wo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.**

---

Are you a Mechanic ?—If so you must want Tools, now or soon!

Do you intend to put up a house ?—
Then you will require Builder's Hardware!

In either case you cannot do better than call at

**B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores**

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

---

**J. C. VAUGHAN**

Ti ile-ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna : bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ :

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oṣe fun ọ lati re yan irin-iṣẹ tirẹ nibẹ ba kanna

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atari-Ajanaku lọjọ to ti pẹ : bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai ! bi o ri orişirişi Ọkọ ti o ri ra nibẹ ha yio ṣe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

**Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.**

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office 24,* Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/0d | 7/ |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d | [illegible] |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

ORO, EPA ORO MBỌ!

Ọgọrọ enia ni nwọn wa fi ẹjọ awọn ẹgbẹ ti nwọn npe ni Alikali sun wa wipe ki a ṣe kilọkilọ fun wọn nipa ti ija ọbẹ ti a sọ fun ni pe nwọn ja ni akoko ọdun Keresimesi lọsẹ yi ni apa Ita Balogun, a gbọ pe pupọ enia lo damu, papa, awọn obinrin ti nwọn wa lapa ibẹ nigbati idagiri ija na ba wọn: bi ọdun ba de, o yẹ ki a yọ ṣugbọn bi ti fifi ọbẹ tabi ohun ọṣẹ miran ma ṣe enia leṣe ke. Ẹnyin Ẹgbẹ Alikali, dẹ dẹ o! dẹ dẹ o!! ija ele, ka ma ri loju, ka ma ri.

## IWA—AGBARA TI ẸKỌ ILE NI.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KẸRIN.

Nipa ṣiṣe afarawe, diẹdiẹ awọn afarawe wọnyi a di iwa ẹni nikẹhin. O le dabi ẹnipe awọn afarawe wọnyi ko to tan, ṣugbọn bẹ na ni gbogbo ohun ti a nṣe lojojumọ ti o wa di ara.

Bi a ki i ti ri awọn yinyin kekeke bi nwọn ti nwọ lati oju ọrun, bẹni a ki i ṣe akiyesi awọn iwa kekeke wọnni ti a nhu; yinyin kọkan ti o nkun awọn eyiti o ti wọ silẹ ko kun ni loju, ṣugbọn ti nwọn ba pọ tan, nwọn a di okiti yinyin. Gẹgẹ bẹ ni awọn iṣe wa i bagbogbo, ni ṣisẹ-ntẹle, a wa parapọ di aṣa, a nu enia ṣe rere tabi buburu, olnbori rẹ ni pe, a di iwa rẹ.

Nitoriti iwa iya ni agbara lori iṣesi ati ilosi ọmọ ju ti baba lọ, ni o fi jẹ pe apẹrẹ rere iya jẹ ohun ti o jẹ pataki julọ ninu ile. Eredi ti eyi fi jẹ bẹ ko lọ titi. Obinrin ni o ni ile—abẹ rẹ ni o wa, on nikan ni o ndana yan ibẹ. Agbara rẹ lori gbogbo awọn ọmọ abẹ rẹ ko lẹgbẹ. On ni nwọn a ma wo fun ohun gbogbo. On ni apẹrẹ ati aworan ti i ma wa niwaju won nigbagbo, ti nwọn a si ma wo ti nwọn a ma farawe.

Nigbati Cowley nsọ nipa ti agbara ti ẹkọ ati o[…] ti a kọ ni, ni igba ewe, o fi iwọnyi we gbigbẹ i[…] kika sara igi ti o jẹ odo, eyiti i ma fẹ si bi igi na [...] ndagba. Bi o ti wu ki ohun ti a ko si i lara nigbanu, le kere to, ko le parẹ lailai.

Awọn ero ti a ba gbin si okan ewe, dabi irugbin ti a fi bọ ilẹ, a gbe inu ilẹ fun igba diẹ, a sọ jade, lẹhin na a wa hu jade ninu a yọ gedegbe ninu iwa ninu ero ati aṣa. Bayi ni a ri i pe iwa iya a wa pada di iwa awọn ọmọ rẹ (c f—Ewe ti iya ẹran ba ja jẹ, ohun na ni awọn ọmọ rẹ yio ja jẹ). Bi nwọn fẹ bi nwọn kọ, nwọn a fi ilosi, isọrọsi, iṣesi ati ọna gbogbo gba ti o ngba ṣe nkan, jọ o. Nwọn a gbe aṣa rẹ; iwa rẹ a si han gbangba ninu iwa wọn.

Iwa iya si ọmọ rẹ yi, jẹ ori-ire kan ti awa ẹda ni ti ko si farasin. Agbara rẹ ki i yẹ o si ka gbogbo agbaiye. On ni ipilẹ ẹko ẹda, eyiti o ba si jẹ iya rere, a ba awọn ọmọ rẹ kalẹ. Nigbati nwọ[n] ba bẹrẹ iṣẹ ṣiṣe, ti olukuluku wọn ba tẹwọgba la[...] gboke-gbodo ati iyọnu aiye, ni asiko iyọnu [...] idiwọ, iya wọn ni nwọn yio tọ lọ fun suru[...] nwọn ko tilẹ wa imọran rẹ.

Ẹkọ rere ti o ti ko wọn nigba ewe, a ma gb[...] si i ni ọkan wọn titi lọ, lẹhin ti iya wọn ti ku lọ ti o jin; ani nigbati o ba di pe iya na ti ku pẹ, ti si jẹ pe ẹkankan ni nwọn nranti rẹ, sibẹ aw[...] ọmọ rẹ a wa dide nwọn a si pe ni alabukun [...]

*Koi ti pari.*

*Translated By*

ADEYINKA AJAGBE-[...]

## KERE O! KERE O!! KERE[...]

Tayọtayọ ni a fẹ fi kede fun gbogbo[...] wipe Ile Igbadun ti a sọrọ rẹ ni ọsẹ d[...] (*Native Hotel*) y o ṣi fun gbogbo enia [...] Oluwa. Ni ọjọ wo ni? Nibo ni? [...] 1928, ni 34, Ẹlẹgbata Street, Lagos.

Ẹnikeji lọ wo (*Independent Hall*) [...] pọ nibẹ ẹnikeji mi, a fi bi o ba de ibẹ [...]

Irohin ko to afojuba ọrẹ mi. Ọjẹ na[...]

IWA IHU-EHIN-GAN-KGAN TI IJỌBA NIGERIA HU NI ILU WARRI TO MBẸ LABẸ ABO ASIA ỌBA KING NIPASẸ ỌRỌ OWO-ORI.

## IDABOBO AJA PẸL' ẸKUN.

WOSIKA AṢ'AJẸ-MASẸ SI GOMINA GRAEME THOMSON, K.C.B.

LATI ỌWỌ

HERBERT MACAULAY, C.E.

APA KEJI.

Bi o tilẹ jẹ wipe Adajọ Maxwell gba pe Akpowa omusaṣegun, ẹniti o tutọ si Ọgagun Walker loju lojiji yo tabi kọgila kọlu u, sibẹsibẹ nigbati Adajọ yi nja iwe-irohin *(Daily News)* ti ọjọ kẹjọ oṣu *October* nikoro pe ọkunrin ara Isobo kan ni a sọ pe a ti mọle nibiti awọn Ọlopa pa bi ejo aijẹ, eyiti o mu ki o ku lọjo keji lẹhin ohun ti o ṣẹlẹ yi, alaye ti Ijọba Nigeria, tẹnumọ gidigidi pe ko si otitọ ninu lankẹ ti nwọn ngbe kiri pe ọkunrin ti a ramu na ni ilu Sapẹli ni ọgbọn ọjọ oṣu *September* ku nitori lilu ti awọn Ọlọpa lu u.

A ti fi ofin de molẹ pe ki o ma ja ki o ma ta fun oṣu mejila, a si da silẹ ni alafia, ẹnikan lo paṣẹ fun awọn Ọlọpa pe ki nwọn yinbọn si awọn enia, Oyinbo na si pa ọkan ninu wọn bi adiẹ-ko-sọka, a de ri gbọ laisi ...hiani pe kakiri igbereko ilu Warri, awọn ...ra ilu na s'eja, nwọn si dẹhin kọ ọja rira ...wọ awọn Oyinbo onisowo.

"...Ni ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu *October*, 1927, ...ṣe ikede isalẹ yi ni Warri:—

KERE O!

...fi eyi sọ fun gbogbo enia pe rukerudo ... ni igberiko Warri, awọn Isobo, Ijọ ati ...i nta ofin Kotu Ọmọ-ibi'ẹ laiya, nwọn ...i jẹki awọn enia roju gbọ ti ara wọn ...iṣẹ ekurọ ati owo wọn ti nwọn nṣe.

...nu ipade pupọ ni mo ti la alaye ohun ...ẹlẹ yi fun awon enia, ṣugbọn nwọn ṣe ...an si eṣu, nwọn ṣe eti gbọnin si ẹbọ, ...aṣaju awọn enia wọnyi lo ntan wọn jẹ ...ọn le ṣe ṣiọ si ofin Ijọba ki nwọn si mu jẹ ati pe nipa bibu ẹte lu ofin Ijọba bayi, Ijọba yio tunba lati pa'na ofin owo-ori.

Awọn enia wọnyi kan nwa ibi ara won ni, nitoripe Ijọba ki yio ṣe ai mu ofin owo-ori na ṣẹ.

Mo pa laṣẹ pe yiyọ ṣuti si ofin Kotu Ọmọ-ibilẹ ati awọn ẹniti ko jẹki onisẹ ṣe iṣẹ wọn wolẹ mọsamọsa, Ijọba yio dabo bo awọn ẹniti o nfẹ ma ba iṣẹ wọn lọ, yio si jẹ awọn ẹniti o ba yọ wọn lẹnu niya, ki ẹnikẹni ti a ba dẹruba tabi ti a ni ki o sanwo ni ọna aitọ, ki lọ sọ fun Oyinbo tabi Olori Ọlọpa, Ijọba ni lati paṣẹ ki o si wọlẹ.

W. E. HUNT,

Ajẹlẹ Pataki,

*26 October, 1927.*

Boya Ọgbẹni Ajẹlẹ Pataki, W. Edgar Hunt yi wa ni ile-iṣẹ Sẹkitẹri Ijọba nilẹ yi, ninu gbogbo oṣu *September* to kọja, ṣugbọn o tilẹ pada si Warri ni oṣu *October* laipẹ, lẹhin igbati Akpowa ara Isobo yẹn tutọ si Ọgagun Walker loju ni ilu Sapeli, eyiti ko ṣe oju Ajẹlẹ Pataki na.

Bi o ti wu ki o ri yio jẹ nkan ti o wu ni lati mọ ipade melo ni Ajẹlẹ na pe awọn Isobo, Ijọ ati Ṣẹkiri si, ati ibi melo ni nwọn ṣe ipade na ati irufẹ suru ti Ajẹlẹ Pataki na mu lati ọjọ 5 titi de ọjọ 26 oṣu *October*, 1927, ti enia inu rẹ pọ bi iyẹpẹ.

Ninu iwe-ofin Ijọba Nigeria ori 77, iwe kinni, a fun Gomina Agba laṣẹ lati sọ pe apakan igberiko Nigeria daru, irufẹ ọrọ bẹ si ni lati wa ninu iwe-irohin Ijọba, iyanju ti Ijọba si gba awọn Oyinbo ti o ntọju awọn ilu ni pe, o jẹ iṣẹ awọn Ajẹlẹ Pataki lati ma mu aṣẹ Gomina ṣẹ lalai ti tiwọn bọ ọ, nitorina o jẹ ohun ti o ru ni loju lati ri ikede ti Ọgbẹni W. E. Hunt, Ajẹlẹ Pataki, ṣe, lalai jẹ wipe a ri aṣẹ Gomina ninu rẹ tabi ki o han tabi ki a tẹ si iwe-irohin Ijọba.

Ni oṣu *March* ọdun 1922, ni Gomina Clifford sọ wipe ki awọn Oyinbo ma jẹ amuṣan, ki nwọn ma si gbe ogun kankau

nijọsi, o sọ bayi po:—Jakejado gbogbo ilu ti o wa ni abẹ Igẹsi ni West Africa ni ẹmi titunba fun Ọba King kuro ni yẹsuyẹsu, ẹri yi si jẹ ohun ti mo le fi ogun rẹ gbarı.

OWO AṬO IJỌBA JẸ AGBỌN-'GBẸ OMI OKUN.

Bi owo ti Ijọba nri gba ni ilu Warri ba to, ko je ohun ti o tun yẹ lati tun fi owo-ori lọ wọn, kini o ha si ti ṣe di fifi ẹmi enia ṣofo, ati rukerudo gbogbo fi ṣelẹ ni ilu na, owo apo Ijọba ni Warri io fẹrẹ lati ẹgbẹgbẹrun poun ona ẹgbẹta ti o tun le janrẹrẹ ni ogun odun to kọja (1907) de adọta ọkẹ pọnun nisisiyi, bẹ awọn Ijọ, Isobo ati Ṣẹkiri wonyi ni ọwọ ninu dida owo wọnyi lati inu iṣẹ epo ti nwọn nṣe, lalai ka awọn owo pẹpẹpẹ miran ti o nti inu orişirisi iṣẹ won omiran wa. irufẹ owo ti awọn Ṣẹkiri nda yi pa ete ti Ijọba npa lati tun gba owo omiran lọwọ wọn ni ọna owo-ori mọlẹ, şugbọn gidipa bi o tilẹ jẹ wipe iwọ Gomina fẹ gba owo-asingba ni ọwọ awọn enia wọnyi ti iwa won rẹhin gẹgẹbi Ijọba ti wi, ipa ni gbigba irufẹ owo bẹ fi le ye wọn, eyiti nwọn si le ka si hlọ-lọwọ gba nitoripe awọn enia na ko ṣai ni owo ti nwọn nda sinu apo Ijọba ni ọna ti Enia Dudu lalai si fifi girimọkayi gba lọwọ wọn, gẹgẹbi owo ti ngbin kẹ ninu apo Ijọba ilẹ Enia Dudu, mo fi tọwọ-tọwọ bere pe kiloṣe rati Ijọba ki ifi ọna ti o tu ti o ba la ọran owo-ori yi fun awọn enia wọnyi bikoṣe ki Ijọba ma ta ẹjẹ wọn silẹ?

TITỌJU ẸNI ABẸ ẸNI.

Gomina Nigeria ni lati ma dabo bo isin ati ẹkọ awọn enia, o si ni lati ma dabo bo awọn ninu gbogbo iṣẹ wọn ati awọn ohun ini wọn, ki yio si jẹki ẹnikẹni ṣe wọn ni ijẹa tabi fi aitọ gbogbo lọ wọn.

Ni asẹko yi eyiti o wu Olọdumare lati fi ọbe baba wa nihin, gbogbo ifẹ wa ati alafia awa ọmọ-abẹṣẹ Ọba King dọwọ rẹ, gẹgẹbi aşe gbogbo ilẹ Enia Dudu, o yẹ ki iwọ Gomina ni ẹmi itọju gbogbo awọn ẹniti a fi si abẹ aşẹ rẹ.

O jẹ iṣẹ ẹnikẹni ti o wa labẹ asia Ọba King lati ṣe iranlọwọ fun iwọ Gomina ninu iṣẹ rẹ ti o le yi, ki jijẹ alakoso rẹ lori wa le tu wa ki o si ba wa ati lati se ẹtọ si gbogbo enia lai bẹru ati lai şe ojusaju ki Ọlọrun ki o ran ọ lọwọ.

Aşẹ ti a fun ọ lati şe alakoso igbereko jẹ aşẹ ti yio ma wa alafia gbogbo enia lati pana gbogbo ohun aidara wọnni ti a le şe si awọn mẹkunnu ati awọn nkan ti Ijọba ko fẹ, ma lakaka lati ma gba ẹnikẹni ti o ba fẹ wa si iwaju rẹ, ki o si ma şakiyesi iwa awọn aforanlọ re, maşe ni iwa "Tani ma mu", ki iwọ ko o ma si jẹki awọn ẹmẹwa rẹ ni iru iwa bẹ pẹlu: mo tunba o.

Emi ni tirẹ nitotọ,

H. MACAULAY, C.E.

Gbangan "Kirsten",

Eko, December 20, 1927

---

**OLUSAKIN'S COLUMN.**

**The arrival of Mr. S. Ayodele Thomas**

*Barrister-at-Law.*

We cordially welcome Mr. S. Ayodele Thomas, B.L., (Intermediate Bachelor of Laws of the University of London), who arrived Lagos from England by the German Boat *S.S. Wahehe*, on Saturday the 31st December, 1927.

**Lagos Races.**

December Meeting held on Saturday the 24th, Monday the 26th and Tuesday, the 27th 1927, at 3.45 p.m. each day.

**List of Winners.**

FIRST DAY.

*The Maiden Purse.*

1st Messrs. Minaise & Coates, *Radio*
2nd Mr. M. Halabis, *Herram*
3rd Mr. G. J. Lethem's, *Nimble*

*The Maiden Mile.*

1st Mrs. A. Alakija's, *Wind*
2nd Mrs. A. L. Butler & H. Scott Taylor's, *Beeb*
3rd Mr. Kamil Saidi's, *Jupiter*

*The Railway Cup.*

1st Messrs. Scott Taylor & Bentham's, *Maiwand*
2nd Mr. Joseph George's, *Goodbye*
3rd Major William Thomas, *Queens Royal*

*The Lilliput Stakes.*

1st Mr. G. J. Lettem, *Nimble*
2nd Messrs. Minaise & Coates, *Radio*
3rd Messrs. Minaise Bros. & Nahum's, *Maccace*

*The Lagos Race Club Plate.*

1st M. Kamil Saidi's, *Jupiter*
2nd Messrs. Barrow & Ford's, *Bador*
3rd Mr. Joseph George's, *Black & White*

*The B.B.W.A. Plate.*

1st Mrs. A. L. Butler & H. Scott Taylor's, *Boob*
2nd Messrs. Minaise Bros. & Nahum's, *Say When*
3rd Mr. M. Halabi's, *Touareg*

*The Lagos Race Club Stakes.*

1st Mr. F. George's, *M. Niger 2nd*
2nd Mrs. A. Alakija's, *Wind*
3rd Mr. G. J. Leithem's, *Nimble*

*The Merchants' Purse.*

1st Messrs. Scott Taylor & Bentham's, *Maiwand*
2nd Mr. Joseph George's, *Goodbye*
3rd Mr. M. Halabi's, *Touareg*

*The Southern Provinces Cup.*

1st Mrs. A. Alakija's *Wind*
2nd Mrs. J. Carruthers's, *Onega*
3rd Mrs. R. H. W. Hughes', *Greatheart*

*The Lagos Jubilee Cup.*

1st Messrs. Minaise Bros. & Nahum's, *Maccaco*
2nd Mrs. A. L. Butler & H. Scott Taylor, *Boob*
3rd Miss Layinka Moore's, *Fox Trot*

*The Treasury and Audit Cup.*

1st Mrs. A. L. Butler & H. Scott Taylor's, *Boob*
2nd Mr. Joseph George's, *Goodbye*
3rd Mr. Kamil Saidi's, *Jupiter*

*The Three Furlong Sprint.*

1st Messrs. Minaise & Coates', *Radio*
2nd Mrs. F. Georges', *St Nigen 2nd*
3rd Mrs. R. H. W. Hughes, *Greatheart*

*The Lagos Stakes.*

1st Mr. Kamil Saidi's, *Jupiter*
2nd Mr. M. Halabi's, *Heriam*
3rd Messrs. Minaise Bros. & Nahum's, *Say When*

*The Governor's Cup.*

1st Mr. Joseph George's, *Black and White*
2nd Mr. Joseph George's, *Goodbye*
3rd Messrs. Scott-Taylor & Bentham's, *Maiwand*

*The Farewell Purse.*

1st Mrs. M. J. de Rhodes, *San Carlos*

**Wit and Humour.**

THE JUDGE'S JEST.

Two young Lawyers, both trying to make reputations, as orators, happened to be pitched against each other in argument. Both spoke at great length, and in closing the second speaker remarked that he was sorry to find his colleague on the wrong side, for there was every reason why they should agree.

"We were brought up together, we studied together, and we were born on the same day."

"Did I understand you to say that you were born on the same day?" Asked the Judge. "Yes," came the prompt reply.

"On the very same day?"

"Yes, Sir."

"Then it must have been a very windy day."—N...

OLUSAI...

## INA WỌ'LE OKUNKUN PAR...



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ... lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilek... papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ... ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ ... agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni... ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti... ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o... jafara lati ra atupa meremere yi ti o... electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fada... ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyi... KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ m... gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma... j'oku ologbo.

## *IN MEMORIAM.*

In affectionate memory of our dearly belove... Father

OWEN E. VIDAL

(*Alias* ABUNỌ BURỌRE)

Who breathed his last on the 31st December 19...

The Streams of death has parted us,
The Golden cord of unity has broken,
The shadow of persons may has lost.
Safely and calmly thou art rest,
And thou art pursued towards
the mark, for the prize untold,
We shall meet again

E. FOLARIN VIDAL

**EKO AKETE**

SATURDAY, DECEMBER 31, 1927.

## KI L' ELEKO ṢE?

…udaju ibere oke yi ko ni ṣai ma wa …olukuluku enia lẹkọkan nigbati o ba …ọrọ ti o mu Prince Eṣugbayi Eleko …-sunun ẹ'ọmọ Dosunmu di ara Ọyọ …gangan loni, ṣugbọn gẹgẹbi a ti nsọ ti … ti ntẹ mọ nyin leti nigbagbogbo, ọrọ … ma ro f'ẹgbẹ ni, nitori bi ẹjọ ti wa …ro ni Kotu Apili nilu Ọba.

…i ọsẹ to kọja ri a sọ pe ọjọ kọkanla … to mbọ ni a gbọ pe a fi riro Apili na si; … ni ogidirigbo ọrọ yi sọlẹ nipa orisirisin na ti Ijọba sọ pe Eleko ṣe ti o fi jẹ awọn awọn Alaṣẹ nibi sọ Eleko di Alejo ati tun gbo ni Ode Ọyọ: ohun to ku nisisiyi ni ori nwọ adura ki Ilu le ri aiiun ninu riro ati iwọ fi ọran na; a ko le ṣeṣẹ ma sọ ti ifoju-awọn ti ọpọlọpọ enia nṣe fun ẹjọ banta-banta Ijọba oju ẹlomiran o dabi ki o ri ọkọ ofurufu ye wọ ti o nlọ si ilu Ọba wọ lati lọ jẹ igbadun nitorin ọkan-ko-jọkan ọrọ ti awọn Lọya nwọnko yio ma rojo rẹ silẹ pẹlu Lọya Ijọba Dudaju awọn Adajọ korogba-korogba mẹta gẹgẹpe kini Eleko ṣe ti o fi di ẹni wiwa lọ.

Bi inu ba ti ri sa ni obi nyan; loju pupọ …a, ẹwẹ o dabi ẹnipe ki a ri waya ayọ ojiji … ilu Ọba wa ni ipari ẹjọ na.

Ẹ jẹ ki a fi ori kan ṣajo:

E—ko, ẹ mura ãjo
E—ko, ẹ mura ãjo
K' obi Ilu le yan
K' obi Ilu le yan
Ki Sati k' o gbọwọ.
K' Ọba King k' o pẹ.

---

## IROHIN ODE, JẸBU RẸMỌ.

…wọn Ijọ *Bethel* ni Ode ṣe Ikero wọn ni *Monday* …erindinlogbọn oṣu yi. Ko si bo ti ri ni ayọ … Alufa J. Michael Ọṣọba ti o ṣe wasi; fun … la pupọ.

Ọba Alaye Ode pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ wa jọsin. Nigbati a kọkọ ngbọ ilu, ẹnu ya ni wipe kilo ti ri, esi ti a ri ngba ni wipe Alaye Ode lo nbọ; ko pẹ la ri Awẹsilẹ-doye, ọkunrin gborogọdọ gborọgọdọ, to yọ bi oṣumare lọkan, pẹlu ilu to dun nkikan! Alaye, mo gbadun ẹ! wa pẹ lori oye! igba tirẹ ti dara na! a si ma dara siwaju.

Owo ti a kọjọ ni ọjọ na mu ọpọlọpọ iṣiri wa—Ẹnyin Ijọ Ode—A sọ nyin ni orukọ titun Ọlabọpo, Ọlarewaju.

### ODE UNITY CLUB.

Awọn Ẹgbẹ ọdọmọkọnrin ti a darukọ soke yi ṣe ajọyọ ọdun kini wọn nipa ṣiṣe Isin Pataki ni *Sunday*, ijọ kẹdogbon oṣu yi ni Ijọ *C.M.S.* Alufa S. A. Ogunrinde ti iṣe ọkan ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ na lo gba ni ni iyanju.

Ni ijọ keji awọn Ẹgbẹ ṣe aisun pataki ni Gbangan Idajọ Ilu nibiti gbogbo awọn ọmọde-mẹṣọ pe si.

Ki Ọlorun ko mu ẹsẹ wọn duro.

---

## Ẹ KU ẸWU ỌDUN.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU ]

Mo bẹrẹ f'oji

Oni oloni ni ọjọ ikẹhin ọdun 1927, ọla si ni ibẹrẹ ọdun titun, ọdun 1928.

Ọpọlọpọ enia ko ba ti ri wahala ati idamu pupọ lati ibẹrẹ ọdun yi wa, lai ka ogunlọgọ enia ti o ti goke re orun, ọrun alakeji aremabọ. Sibẹsibẹ, o yẹ ki gbogbo ẹniti o wa l'aye loni, yin Oluwa l'ogo, fun ipamọ ati ãbo Rẹ lori gbogbo ẹda alaye to wa ninu aiye loni.

Gẹgẹ bi ọpọlọpọ ọdun to ti kọja lọ, 1927 yi ko ṣai ṣe gudugudu meje tirẹ, eyi ti ọdẹ nṣe, ani ti a ba tilẹ ranti pe ọdun yi ni ọdun ti Ijọba nfẹ lati sọ ara rẹ di "Wokoko" si wa l'ọrun lori ọrọ esu adaiko, a ko le ṣai pe e ni "Ọdunlami" bi orukọ ọmọ ọlọmọ.

Nitoto ọjọ ijo, ọjọ ere, ọjọ ayọ nla ni o yẹ ki ọjọ oni jẹ fun wa, t'ọkọnrin, t'obinrin, t'ọmọde, t'agba. Ṣugbọn gbogbo ọdun kan gbako ti o kọja, bawo ni a ti lo o si? Iwa agutan ko pa aṣọ eṣi da ha kọ ni pupọ ninu wa nhu nile, l'adugbo, l'ode ati ni Ilu pẹlu? Ani iwa aṣa, iwa ọdajụ, ọdalẹ, ika ati tẹmbẹlẹkun.

Ko si ifẹ atata, bikoṣe iru ifẹ ti a nfẹ adiẹ to ṣe pe ibi pipa jẹ lo mọ. Ṣọṣi ke ke ke, Mọṣalaṣi

sọ, so, sọ, pabo, "Dunia" ni olukuluku enia nba klri.

L'akoko bayi, akoko ko si tobẹ lati kọ iwe tabi lati ka tun ọpọlọpọ enia, nitorina a ki yio jẹ ki wosika wa ọsẹ yi gun rara. Ṣugbọn a ko le ṣai gbadura fun gbogbo Ilu pe :—

Ki o le wu Oluwa lati ṣe ọdun titun ti ao bọ si lọla yi ni ọdun rere fun wa. Ki O ṣe ni ọdun ifẹ, ọdun owo, ọdun ọmọ, ọdun alafia, ati ọdun iwa bi Ọlọrun. Ki O le wu Oluwa Ọbangiji lati pese fun gbogbo alaini P'okonrin, l'obinrin, ki O le fi àiya ile balẹ fun gbogbo wa, ki o ṣẹri ibukun alafia si Ilu, ki a maṣe ri iku, ki arun maṣe gbe wa de, ki agbara okunkun ma si le ni agbara lori ẹnikẹni ninu wa.

Ki o le wu Oluwa lati gbe alaisan dide lori akete amodi rẹ, ki O jẹ ki agan fi ọwọ ṣe osun ọmọ, ki O toju gbogbo ṣaṣiwẹrẹ to wa nilẹ ati awọn obi wọn pẹlu. Ki O maṣe fun ẹnikẹni ni gbe iya gbe iya tabi babarinsa ọmọ, ki O si jẹ ki alẹ olukuluku wa dara ju owurọ lọ, *Amin* bẹni ki o ri.

Buroda, ọdun mi da? Sisita, ọdun mi da? Ọdun yi ọdun rere, gbai la o ma l'owo l'ọmọ, Aṣẹ.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## ỌMAKỌLI ATI ỌLỌLA GOMINA.

LATI ỌWỌ KEKERE- AWO.

Si Oniwe-irohin "Eko Akete,"

Mo bẹrẹ foji o,

Ọgbẹni wa Habati Makọli abi-gege bọmọlẹru ọkunrin ti a fi nṣepe ọkunrin o ma fogbẹ sinu iwe irohin ojojumọ *Daily News* ti ọjọ 22 oṣu yi, nipa iwa "Tanimamu" ti o ni ara awọn ọmọlọju Alaiye luwa nhu ni apa ọna ilu awọn Isobo lori ọran owo-ori sisan.

Iwe yi tu aṣiri rukerudo ti owo-ori gbigba nfẹ mu wa nile loko loke ati lodo kakiri ilẹ *Nigeria*, awọn agbagba nwọn a ma pa owe pe igi gangan-ran ma gun ni loju lati okere ni a ti nlọ ọ bẹni ọrọ ti Makọli ba Ọlọla Gomina Graeme Thomson sọ ri loju wa eyiti o yẹ ki awa tikalarawa sọrọ diẹ le lori.

Lati kekere Ajanaku li erin ti 'pọ ju ẹfọn lọ ṣugbọn bi erin ba fẹ huwa bi ganbanku rẹ ti pọ ju ẹfọn lọ bi ẹfọn ko tilẹ ni agbara lati ba erin ko'ju, erin kole ni ki ẹfọn maṣe kigbe, iyẹn ṣoro gidigidi.

Lọjọ ti oni Ijọba Igẹsi ni erin fun wa, awa ẹfọn, owo-ori ti Ijọba nfẹ gba lagbara lo da iwa "Tanimamu" nitori nigbati ẹfọn nsọ w iwọ erin ohun ti o fẹ mu on lagbara lati ṣe nkole ṣe, ti erin si sọ wipe panpa-obele li on yio fẹ mu iwọ ẹfọn lati ṣe ifẹ inu on njẹ ti o ba da bẹ, ẹfọn ko ni kigbe fun ọdẹ bẹ pe ki o ba awọn yanju rẹ? A bere ni, bẹni ọrọ owo-ori ti Ijọba Igẹsi fi ake kọri pe awọn yio m awọn enia nihin lagbara lati san yi jẹ.

Ọgbẹni Makọli tu aṣiri gbogbo rukerudo ti ṣẹlẹ ni ilu Ogele ni itọ Forcados, bi o ti jẹ wip awọn olopa ko ibọn lọ si ilu yi ti nwọn si d "Yesufa" si bẹ lẹhin ti rugudu ti o ṣẹlẹ ni ile Warri papa ni lọloyi tobẹ ti nwọn fi sọ wipe nwọn tun yin awọn enia nibọn lori oran owo-ori y kanna, ti o tun fi dogun ohun ti nwọn ni lati bu owo sisan fun awọn omiran ninu wọn ti nwọn sọ wipe o gboju gangan nigbati ọran na ṣẹlẹ ati p o yẹ ki a mọ bi iwa ti awọn ọmọloju King nhu n apa ilẹ awọn Isobo ati awọn ibi gbogbo ti a w wọnyi ati pe gegẹbi ofin ilẹ enia dudu ti nwọn bu owo sisan bi P nun marundinlọgọrin fun wọn ni sisan si apo Ijoba titi ọjọ mẹrinla ti nwọn bu owo yi fun wọn, lẹhin ti nwọn sọ wipe nwọn pa enia meji tabi mẹta ni Ogele dajudaju iwa "Tanimamu" ni erin fẹ hu fun ẹfọn, odẹ ni Ọlọla Gomina on ni ẹniti yio yanju ọrọ yi.

### OWO-ORI.

Nipasẹ ọrọ owo-ori yi ni ọrọ ti ẹgbẹ Dẹmọ tabi ti Ọgbẹni Makọli sọ ju ni Ajọ ti nwọn ṣe lọ ni ọjọ kẹwa oṣu yi, kini ohun ti o tẹnumọ julọ ni akata kiti ti oran na nfẹ mu wa, eyiti o han fun gbogbo enia pe nwọn nṣe hila-hilo ọkan si i.

O ni koi pẹ yi ni awọn ngbọ wipe ọran na ti de apa ilu Onitsha ati ilu Agbor a ko tun le ṣeṣe ni a nsọ ti ilu Ẹpe ati ilu Badagry mọ, lori gbogbo ọran yi a nsọ fun Ijọba wipe enia kole fi agbara le'ko ti o ku, lẹhin igbati awọn Ijọba tikalarawọn papa ko ṣe a'ai mọ inu babu ti ilu wa loni nipa airisanṣekan ti o wa fun ogunlọgọ enia ani nipa ai ta ọja ati ai ra, ani nipa ailo dede owo, ani nipa opẹlọpọ ọmọluwabi ti o ti ku si iduro nigbati o nronu irufẹ bukata rẹpẹtẹ ti on nran ni kọrọ iyara on ti tọrọ ko si ba kọbọ lọwọ lati ma fi ṣe ọmọ enia ati irufẹ awọn ọmọ, aya ati ẹbi gbogbo ti o rọgba ka on ti o si jẹ wipe Oluwarẹ lo ngbe ẹru gbogbo ti oluwarẹ ni lati gbe lori ọna gbogbo ti a ka wọnyi, tobẹ ti a si nla alaye wọnyi ye Ijọba, ṣugbọn sibẹsibẹ ti Ijọba fi ake kọri pe ọrọ ti o ti ku li a nsọ, bẹ bi o ti wu ki o ri enia kole fi agbara le oko ti o ti ku, a fi ẹniti o ba fẹ huwa alagbara lo ni aiye fun enia.

Nitotọ li atetekọṣe li iran enia funfun ti mọ-ju-wọn-lọ lọpọlọpọ fun iran enia dudu ṣugbọn sibẹsibẹ nigbati awa enia dudu fẹ gbe Ijọba le iran enia funfun lọwọ, kosi Ijọba meji

sumu gbe iran enia dudu le lọwọ lati ma bobo wa bikoṣe Ijọba Igẹsi, kini a npe ni abo irọra ati alafia ki iṣe ijangbọn bẹni ki isi iṣe ahala ijangban wo lo tun ja eyi lọ, lẹhin igbati a ki a ma toju eni ki a ma dabo bo ni eyi jẹ ohun Ijọba Igẹsi i ba tubọ fi si ero dara dara lẹhin gbati a nke ti a nyan fun Ijọba wipe a koi ti ni gbara to lati san owo-ori kun owo-omi ati owo ẹpẹpẹ ọmiran bi owo-bode ti a tun nsan kun, owo-bode ti o jẹ wipe o fẹrẹ ju owo ti oluwarẹ papa fi ranṣẹ oja ni ilu oyinbo papa lọ nisisiyi, bi Ijọba Igẹsi ko ba fẹ lo wa ni ilo omi ojo nipa ofin afi agbara gba ti nwọn tun nfun wa lo le oni, o tọ o ye ki nwọn ranti ẹhin ani ni igbati Ọba Queen Victoria yio fi gba ilu enia dudu lọwọ Ọba Dosumu ti awọn Ọba mejeji yi si ba ara wọn ṣe adehun pọ gẹgẹbi ọrọ tẹgbọn-taburo, ani ki nwọn ranti wipe nwọn ko ba Dosunmu ṣe adehun po wipe ti o ba di ni lodun 1928 lẹhin ọdun 1861 ti awọn ṣe adehun pọ wipe awọn yio ma gba owo-ori lọwọ awọn enia rẹ ni tulasi kayandoro, eyiti ko ba si fẹ san ọna ti awọn ba fi ju wọn lọ ni awọn yio fi gba a, bi awọn ba fẹ awọn le ko panapana tabi Ọlọpa si ode, bi awọn ba fẹ awọn le paṣẹ fun awọn Ọlọpa ti awọn ni pe ki nwọn ko ibon ki nwọn si ki ota si ninu bi awọn ba yin ota si ofurufu lati fi halẹ mọ wọn, bi nwọn ko ba si gbọ ilẹju awọn le yinbọn si ibikibi ti o ba wu wọn, bi ibon ba fẹ o le ba ẹnikẹni adonkiya, tabi bi eyiti o ba fẹ ṣe oju gangan awọn le fi aṣẹ Ọba King mu ki awọn si ni ki o san owo iyekiye titi iseko ti awọn ba fẹ, ti oluwarẹ ko ba si sanwo na awọn le fi pa itukitu ti o ba wu awọn gẹgẹbi aṣẹ tabi agbara ti awọn ba ni.

Bi o ba jẹ wipe gẹgẹbi a ti sọ yi kosi ninu a ndabo bo ni kosi ninu irora ati alafia ani ti ko ba si ninu adehun ti Ọba Dosumu pẹlu Ijọba Igẹsi jumọ ṣe pọ, njẹ awa ri si pe ki Ijọba Igẹsi jọwọ ki nwọn tun ọran owo-ori yi dáro daradara.

A nsa fun rukerudo ti ọran yi le ma ti owo Ijọba ṣẹ bi iru eyiti a nwi yi, ni iwọn igbati Ijọba ba ni ki oloko le oko rẹ ti o ti ku lagbara, ti o si jẹ ohun iṣoro gidigidi lati le ko ti o ti ku eyiyi ni pe bi Ijọba ba ni ki nwọn san owo-ori nibikan, ti awọn ara ilu na si nso wipe kini awọn yio ta, kini awọn yio ra, iṣẹ wo ni awọn nṣe, owo (*Trade*) wo ni awọn yio ṣe lati fi san owo-ori ti Ijọba ba fẹ gba.

## OLỌLA GOMINA!

Enyin ni aṣoju Ọba King George ni ilu Oyinbo nihin loni, abẹ abo iwọ Ọlọla Graeme Thomson gbogbo ilẹ *Nigeria* mbẹ loni, a mọ wipe aṣẹkaṣẹ o ba wu ọ ni o le pa li o si le wolẹ gẹgẹbi ara ti o gba lati ọdọ (*Secretary of State*) ni aṣoju Ọba Alaiyeluwa ti o si jẹ ọga fun Gomina ti o wa fun gẹgẹbi ọnọloju Igẹsi.

Gbogbo ilu lo wa ninu hila-hilo ọkan eyiyi ni aibalẹ aiya nipa ti ofin owo-ori ti e fẹ mu awọn enia nihin ati igbereko rẹ san lagbara gẹgẹbi ajọ Igbimọ ti nwọn ṣe loju igbakeji rẹ ti o njẹ Ọlọla F. M. Baddeley lojọ 23 ati 24 oṣu August ti awọn Aṣoju ti ilu yan si Igbimo (Ọlọla Dokita Jones ati Ọlọla Dokita Caulcrick) gẹgẹbi anfani ti Gomina Hugh Clifford fun wa nihin ki o to pari iṣẹ tirẹ nihin, fi itara sọ kulagbe ọrọ lati fi gba ofin owo-ori yi kalẹ lọwọ Ijọba, ṣugbọn sibẹsibẹ ti ilara rẹ na ko muko nipa didiro fun ọran yi ti awọn aṣoju Ijọba ni kansulu si jẹki ibo gbigba owo-ori ni ilẹ yi mu ti awọn Ọlọla iyoku ti nwọn ko fẹ lọwọ si iru ofin yi nipa pipọ ti nwọn pọ ju ara wọn lọ nigbati ọran yi tun de Kansulu lojọ ti a wi yi lẹhin ti ajọ Igbimo ti awọn tiṣe ninu oṣu April to koja lo yi eyiti awọn enia wa sa agbara ni Kansulu lati tẹ ofin owo-ori oni-ṣile mẹwa-mẹwa ị dodun fun okunrin ti o ba ti to ọmọ ọdun mẹrindin-logun ti Ọlọrun si fun wọn ṣe, ki awọn Igbimo kekere ti Ọlọla Gomina yan lati tun ṣe ṣawura le ọran yi lori, eyiti kosi si awọn enia mẹta nibẹ (Ọlọla Robbert Irving, Ọlọla Becker ati Ọlọla Eric Moore) lara awọn ẹniti Ọlọla Gomina yan si idi ọran yi, gẹgẹbi nwọn ti ni ero pe oṣu October eyiyi ni oṣu keji si oṣu August ti nwọn ṣe Igbimọ ni nwọn yio ṣe Kansulu ti nwọn ko si le reti awọn Ọlọla mẹtẹta yi ki Ijọba to ṣe bi iwarapapa loju wa fi jẹki nwọn yara tẹ sinu iwe iroh in Ọba wipe "*Income Tax*" Owo-Ajulo ni awọn tun yi owo-ori si ti ofin yi si koja lẹhin awọn Ọlọla mẹtẹta ti a daruko, eyi dabi aiduro si ori alukawani to loju awa enia tabi awọn ẹniti ko tun mọ bi ọran na tilọ si, lẹhin igbati a ti jumọ gbe ṣawura le wọn lọwọ pọ.

Owo-ori ti Ijọba ni awọn yio ma gba kakiri Igbereko ila lo nmu irọkẹkẹ wa ba awọn enia ni ilu ani eyiti o mu ki gbogbo enia ma ko ominu.

Gẹgẹbi ipinu awọn ẹgbẹ Demọ ẹgbẹ ti a ri wipe awọn ni ọgbagba ti ngba ara ilu "*Defender of Rights and Liberties*" ni wipe awọn yio ṣe kokari lati wa ba nyin sọro ni itubi inubi ti egun npe ni iyekan nipa dugbedugbe owo-ori ti o nfi ni kakiri ilẹ *Nigeria* olubori rẹ ni ilu Eko, ati pe bi esi ti awọn ba gba lọdọ Gomina ko ba mọyan lori to ni tiwọn, awọn yio fẹ ki Gomina lọwọsi iwe-ẹbẹ ti awọn ba ṣe lati fi ranṣẹ si Sekiteri-agba ni ilu Ọba, bi awọn ko ba si ri idi iwe-ẹbẹ ti awọn ba ṣe, awọn yio gbaradi lati mu ọna ilu Oyinbo pọn, ṣugbọn bi Gomina ba tẹ awọn lorun nihin lau-lafia kosi wipe nwọn tun nfẹ bẹsẹ sọrọ si ilu Ọba nibẹ mọ.

Owe awọn Yoruba wa kan nsọ wipe agbara adiẹ ni alamu fi ṣmu'mi lagbada, Ọlọla Gomina iba jọwọ ki o fiye denu ki o gbọ gbogbo aroye ti a nṣe yi nipa ọran ofin owo-ori yi, ki a le ma wa ni omnira ara wa ani ki a le kuro ninu hilahilo ọkan ti o nṣe olukulu wa nipa ọran yi, lẹhin igbati o jẹ

nijosi, o ... ti o wa ...sumu gbe iran enia dudu le lowo lati ma ...bobo wa bikoşe Ijoba Igesi, kini a npe ni abo irora ati alafia ki işe ijangbon beni ki isi işe abala ijangban wo lo tun ja eyi lo, lehin igbati a ... ki a ma toju eni ki a ma dabo bo ni eyi je ohun ... Ijoba Igesi i ba tubo fi si ero dara dara lehin ...bati a nke ti a nyan fun Ijoba wipe a koi ti ni ...gbara to lati san owo-ori kun owo-omi ati owo ...

Bi ...epepe omiran bi owo-bode ti a tun nsan kun, to, ...owo-bode ti o je wipe o fere ju owo ti oluware ...papa fi ranşe oja ni ilu oyinbo papa lo nisisiyi, ...bi Ijoba Igesi ko ba fe lo wa ni ilo omi ojo nipa ...ofin afi agbara gba ti nwon tun nfun wa lo le oni, ...o to o ye ki nwon ranti ehin ani ni igbati Oba Queen Victoria yio fi gba ilu enia dudu lowo Oba Dosumu ti awon Oba mejeji yi si ba ara won şe adehun po gegebi oro tegbon-taburo, ani ki nwon ranti wipe nwon ko ba Dosunmu şe adehun po wipe ti o ba di ni lodun 1928 lehin odun 1861 ti awon şe adehun po wipe awon yio ma gba owo-ori lowo awon enia re ni tulasi kayandoro, eyiti ...ko ba si fe san ona ti awon ba fi ju won lo ni awon yio fi gba a, bi awon ba fe awon le ko panapana tabi Olopa si ode, bi awon ba fe awon le paşe fun awon Olopa ti awon ni pe ki nwon ko ibon ki nwon si ki ota si ninu bi awon ba yin ota si ofurufu titi fi hale mo won, bi nwon ko ba si gbo ileju awon le yinbon si ibikibi ti o ba wu won, ...bi ibon ba fe o le ba enikeni adonkiya, tabi bi eyiti o ba fe şe oju gangan awon le fi aşe Oba King mu ki awon si ni ki o san owo iyekiye titi ...iseko ti awon ba fe, ti oluware ko ba si sanwo na awon le fi pa itukitu ti o ba wu awon gegebi aşe tabi agbara ti awon ba ni.

Bi o ba je wipe gegebi a ti so yi kosi ninu a...ndabo bo ni kosi ninu irora ati alafia ani ti ko ba si ninu adehun ti Oba Dosumu pelu Ijoba Igesi jumo şe po, nje awa ri si pe ki Ijoba Igesi jowo ki nwon tun oran owo-ori yi daro daradara.

A nsa fun rukerudo ti oran yi le ma ti owo Ijoba şe bi iru eyiti a nwi yi, ni iwon igbati Ijoba ba ni ki oloko le oko re ti o ti ku lagbara, ti o si je ohun işoro gidigidi lati le ko ti o ti ku eyiyi ni ...pe bi Ijoba ba ni ki nwon san owo-ori nibikan, ti awon ara ilu ni si nso wipe kini awon yio ta, kini awon yio ra, işe wo ni awon nşe, owo (*Trade*) wo ni awon yio şe lati fi san owo-ori ti Ijoba ba fe gba.

OLOLA GOMINA!

Enyin ni aşoju Oba King George ni ilu Oyinbo ...loni, abe abo iwo Olola Graeme Thomson gbogbo ile *Nigeria* mbe loni, a mo wipe aşekaşe o ba wu o ni o le pa li o si le wole gegebi ...ara ti o gba lati odo (*Secretary of State*) ni aşoju Oba Alaiyeluwa ti o si je oga fun Gomina ti o wa fun gegebi onoloju igesi.

Gbogbo ilu lo wa ninu hila hilo okan eyiyi n aibale aiya nipa ti ofin owo-ori ti e fe mu awon enia nihin ati igbereko re san lagbara gegebi ajo Igbimo ti nwon şe loju igbakeji re ti o nje Olola F. M. Baddeley lojo 23 ati 24 oşu August ti awon Aşoju ti a yan si Igbimo (Olola Dokita Jones ati Olola Dokita Caulcrick) gegebi anfani ti Gomina Hugh Clifford fun wa nihin ki o to pari işe tire nihin, fi itara so kulagbe oro lati fi gba ofin owo-ori yi kale lowo Ijoba, şugbon sibesibe ti ilara re na ko muko nipa didibo fun oran yi ti awon aşoju Ijoba ni kansulu si jeki ibo gbigba owo-ori ni ile yi mu ti awon Olola iyoku ti nwon ko fe lowo si iru ofin yi nipa pipo ti nwon po ju ara won lo nigbati oran yi tun de Kansulu lojo ti a wi yi lehin ti ajo Igbimo ti awon işe ninu oşu April to koja lo yi eyiti awon enia wa sa agbara ni Kansulu lati te ofin owo-ori oni-şile mewa-mewa I dodun fun okunrin ti o ba ti to omo odun merindin-logun ti Olorun si fun won şe, ki awon Igbimo kekere ti Olola Gomina yan lati tun şe şawura le oran yi lori, eyiti kosi si awon enia meta nibe (Olola Robbert Irving, Olola Becker ati Olola Eric Moore) lara awon eniti Olola Gomina yan si idi oran yi, gegebi nwon ti ni ero pe oşu October eyiyi ni oşu keji si oşu August ti nwon şe Igbimo ni nwon yio şe Kansulu ti nwon ko si le reti awon Olola meteta yi ki Ijoba to şe bi iwarapapa loju wa fi jeki nwon yara te sinu iwe iroh o Oba wipe "*Income Tax*" Owo-Ajulo ni awon tun yi owo-ori si ti ofin yi si koja lehin awon Olola meteta ti a daruko, eyi dabi aiduro si ori alukawani to loju awa enia tabi awon eniti ko tun mo bi oran na ti lo si, lehin igbati a ti jumo gbe şawura le won lowo po.

Owo-ori ti Ijoba ni awon yio ma gba kakiri Igbereko ilu lo nmu irokeke wa ba awon enia ni ilu ani eyiti o mu ki gbogbo enia ma ko ominu.

Gegebi ipinu awon egbe Demo egbe ti a ri wipe awon ni ogbagba ti ngba ara ilu "*Defender of Rights and Liberties*" ni wipe awon yio şe kokari lati wa ba nyin soro ni itubi inubi ti egun npe ni iyekan nipa dugbedugbe owo-ori ti o nfi ni kakiri ile *Nigeria* olobori re ni ilu Eko, ati pe bi esi ti awon ba gba lodo Gomina ko ba moyan lori to ni tiwon, awon yio fe ki Gomina lowosi iwe-ebe ti awon ba şe lati fi ranşe si Sekiteri-agba ni ilu Oba, bi awon ko ba si ri idi iwe-ebe ti awon ba şe, awon yio gbaradi lati mu ona ilu Oyinbo pon, şugbon bi Gomina ba te awon lorun nihin lau-lafia kosi wipe nwon tun nfe bese soro si ilu Oba nibe mo.

Owe awon Yoba wa kan nso wipe agbara adie ni alamu fi nmu'mi lagbada, Olola Gomina iba jowo ki o fiye denu ki o gbo gbogbo aroye ti a nşe yi nipa oran ofin owo-ori yi, ki a le ma wa ni omnira ara wa ani ki a le kuro ninu hilahilo okan ti o nşe olukulu wa nipa oran yi, lehin igbati o je

A ko fẹ lati ri a bako ohunkohun to le mu ni ranti oko ẹru, tabi oko ọta.

Nipaṣẹ awọn ilu apa Kamaruns ti nwọn ti gba lọwọ Jamani lakoko ogun, eyikeyi ti Sẹria (Equity) ba da pada fun wọn nibẹ, laisi ani-ani, o yẹ ki a da a pada fun wọn.

A ko wipe Maleka ni oyinbo Jamani, bẹni a ko si rope ẹnikẹni le fini u fen'do pe nwọn ni Aṣitani, Ija lo de l'orin d'owe!

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

## AJASA ATI JONES, OṢUPA ATI ORUN.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Lori ibiti a gbe ṣọrọ de ni ọsẹ to koja ni wipe, Ọlọla Ajasa sọ ni Kansulu wipe awọn kan awọn enia rere ti o fe wa si kansulu, ṣugbọn awọn kan [illegible] ieki nwọn le dibo fun wọn ni ilu, lori ọrọ yi gan [illegible] Ajasa ati Ọlọla Adeniyi-Jones.

Mo ro wipe Ọlọla Ajasa ko ro ọrọ na wo daradara, ti o ba si ro wo ki o to sọ bẹ, nko ro wipe o yẹ fun Ọlọla kan ki o ma pe irufẹ ede baun jade lẹnu, ni iwọn igbati o jẹ wipe lori ọrọ nipa owoori ti Ijọba nfẹ gba ni ilu yi ni nwọn nsọrọ le lori, ki iṣe ọrọ wipe i olukuluku nwọn ma wa jirẹbẹ wipe ẹnikan ni enia rere tabi ẹnikan ko ni enia rere ni arin ilu ti ko yẹ fun ilu lati dibo fun tabi ti o dara lati dibo fun, loju ti awa ọrọ ẹgan ni eyi jọ.

Nitorina bi a ba ni ki Ọlọla Kitoyi Ajasa jọwọ sọ awọn enia rere ti nwọn nfẹ wa si Igbimọ ti awọn kan ko jẹki nwọn le dibo fun wọn, o buru tabi ko buru?

Ṣiwaju ibere ọrọ wa, bi nwọn tiṣe dibo fun awọn Ọlọla Dokita Jones lọ si Igbimọ larin ilẹ yi ni September ọdun 1923, kosi eyiti o ṣehin wa nibẹ, ni igbati Ọlọla ologbe Loya Shyngle si ku lọdun to koja, ti nwọn si tun fẹ dibo fun ẹniti yio ba gbipo ologbe Shyngle ẹwẹ, kosi eyiti a ko ri tan nibẹ, ki a ba wipe, idibo ọdun 1923 ati ti ọdun 1926 ni oṣu April, ẹnikan ni ko ẹnikan wipe iwọ lagbaja iwọ tamẹdu yi bi o ba fẹ dibo, ninu awọn ti nwọn nmura lati lọ si Kansulu yi, ẹnikan ni o yẹ wipe ki o dibo fun, ẹnikan ni ko yẹ wipe ki o dibo fun, kosi eyiyi nibẹ, bi ko ba si jẹ gẹgẹbi a ti nwi yi, ki Ọlọla Ajasa jọwọ ki o sọ fun wa ni gbangba.

Nitori eyi ti a sọ yi, o da emi nikan loju to ada ohun ti o si fi da mi loju ni wipe,

Ni asiko ti a fẹ dibo lọdun 1923, awọn balogun Wipe olotu ẹgbẹ Dẹmo, ko sọ fun ọmọ ẹgbẹ yi silẹ ni [illegible] awọn mẹwa ti nwọn lọ ti oruko wọn awọn mẹ[illegible] Municipal yi wipe awọn fẹ lọ si Igbimo, Loya Eric [illegible] ni iwonyi:—Ọlọla ologbe Shyngle, Adeyẹmọ Alakija, ologbe, Dokita Adeniyi Jones, Loya (of Ikija) [illegible] Harvey, C. da Rocha, oyinbo Mulford, Dokita Ọbasa ni ki nwọn dibo [illegible] Ajọnlẹ-wọnlẹ Agbebi, A. M. fun, gẹgẹbi a ti wi [illegible] ni ofin'i M. B. Wilson, lagbaja [illegible] tẹsẹ wọnwọn ko gbọdọ dibo

Lẹhinna ẹwẹ ti Ọle pẹ ni ilẹ

Ijọba ti ni ki nwọn yan ẹni rere [illegible] awọn mẹrin nwọnyi Ọlọrun rẹ Lasan, [illegible] Igbimọ, Dokita Caulcrick [illegible] Adeyẹmọ Alakija, Peter Thomas [illegible] ologbe Agbebi, dajudaju si [illegible] idibo fun awọn enia mẹrin yi, lọjọ 30 April [illegible] 1926, kosi ẹniti o lọ si idalẹ nigbana ninu gbọgba [illegible] wa, ni igbati awọn ẹgbẹ Dẹmo ṣe ajo ni Ebute [illegible]:— ti nwọn si ni awọn nreti ẹniti o ba fẹ lọ si Igbimọ, mo ro wipe bi Ọlọla Ajasa ko ba lọ si idalẹ ki idalẹ, yio ma gbọ bi mo ti nla ọrọ yi nisisiyi.

Eyi ki iṣe ọrọ-ija ki iṣe ọrọ-ita, ki Ọlọla Ajasa jọwọ sọfun wa ti o ba ṣe wipe ọrọ rẹ o ro, o gun rege ni ikun rẹ ki o to sọ ni Igbimọ nipa o ṣe awọn enia rere ko ṣe awọn enia rere kan, awọn enia rere gan ti o fẹ dibo lati lọ si Kansulu, ti awọn kan ko si jẹki nwọn dibo fun wọn, ti o ba jẹki a mọ awọn oluwarẹ, lẹhinna ki o jọwọ ki o dakun ki o jẹki a mọ awọn ẹniti o pe gbogbo awọn ẹniti o fi oruko si iwe lọ si Municipal ti Ẹgbẹ Dẹmọ fi ranṣẹ jọ si yara kan wipe, ibo ni ẹ fẹ di yi o, barato lagbaja yi ni ki ẹ i [illegible], tamẹdu ni ẹ ko gbọdọ dibo fun, ẹniti o ba di [illegible] fun oluwarẹ gẹgẹbi awọn ti ṣe ikilọ yi, ilẹ yio ma gi ju oluwarẹ lọ.

Ta lo mà wipe eyi dabi ilọ ti ẹnikan tabi Ẹgbẹ Bombata Ẹgbẹ iroko bi[illegible] igi ani ẹgbẹ oloko ṣikata baba agbado, ki fun awọn ẹniti o dibo, ti nwọn si ṣe ojusaju dibo fun ologbe Loya Shyngle, Loya Moore ati Dokita Jones nigbana tabi fun Dokita Caulcrick ni ọdun to koja, nitori ki ilẹ ma ba ga ju oluwarẹ lọ, ti nwọn ko si dibo fun awọn meji iyoku, tabi fun Loya Alakija, ologbe Agbebi ati ogboni Peter Thomas onile gagara ti o koju si ile-iṣẹ Loya Ajasa papa.

Ọlọla Loya Joseph Egerton Shyngle ti awọn ilu dibo fun lakọkọ to di ologbe loni, ara awọn ẹniti ẹgbẹ Dẹmọ—Ilu dibo fun ni iyen, o wa ku Ọlọla Loya Eric O. Moore, Ọlọla Dokita C. C. Adeniyi-Jones, ati Ọlọla J. A. Caulcrick lo wa loju igba, nisisiyi, ki Ọlọrun si sun ẹmi wọn siwaju fun wa ki o si sun ti awa na si iwaju fun wọn ki Ọlọrun si ma ṣọ olukuluku wa ni igbi-aiye wa yi, amin.

Wayi o! ki Ọlọla Ajasa jọwọ ki o ye ki o sọfun wa irufẹ ipo wo ni Ọlọla Lova Moore, Ọlọla Jones ati Ọlọla Caulcrick wa ni ilu yi papa ninu ẹgbẹ Democratic Party, ipo ẹni palanta ni nwọn wa ni, tabi ipo enia rere? Ipo ọlotẹ ni tabi ipo dẹabi sotọ? Ipo ẹniti nwọn nfẹ rere ilu yi nu oni-bẹkọ? Ipo oni-Munafiki ni tabi ...ọ ni tabi Mọnani, ipo asorunwaju-pọ-mọ-ti 'r gbe ilu rẹ kọ ipo ẹniti o nwa oju're lodọ awọn k... ipo ẹniti o nfi si ori igi tabi asọ lori Rack, t... owo lai gbeyawo, ojojumọ ṣe Awowo lai ... ...mbo pap lai ko'mọ jade? ...o wa ni ile

Ninu gbogbo ... nwọn tun nf... wọnyi, ti Ọlorun ba awọn ẹniti ...n ranti ẹhin a...8 to mbọ, ti aseko loni ba to. t...ia yio fi gba ilu eni...o fun awa ara ilu yi ohun ti a fẹ ki a Ọba mejeji yi ...ba tun fẹ dibo titun orukọ ẹniti o ba ... oro tẹẹ... je eni... rere loju rẹ sode wipe awọn ẹniti on Ọlọla L... ...dun Ajasa fẹ ki ilu Eko yi ran lọ si Kansulu ni ... ...ma gba ...i ni lati dibo fun wọn, gẹgẹbi aṣẹ Ọlọla ... ayandọ ... ọmọba kan ati ojoye tabi aṣẹ awọn ọmọbile ... Ọlọla Ajasa ni nwọn kọ iwe wipe owo-ori ti Ijọba nfẹ gba tẹ awọn lọrun, ki Ọlọla Ajasa tun wa lọ ko awọn enia lati ọna Oworonṣoki tabi Agbadayigi tabi ibi iyi o wu ti nwọn fi Ọlọla Ajasa ṣe Aṣoju ni Igbimọ wipe ki nwọn wa ran awọn ara Eko lọwọ lati dibo fun ẹniti o ba fẹ ki gbogbo wa ba le to lati dibo ti o ba ya.

Eyi lo yẹ ki Ọlọla Ajasa tokere mura si tẹlẹ nisisiyi, ki gbogbo bi o ba ti nfẹ le ma lọ tara, ki o ye jirẹbẹ ni Kansulu wipe o ṣe! awọn ẹni atata kọ ni nwọn dibo fun, nigbana ofin eyi o wu ti Ijọba ba fẹ so ni ilu, gbogbo yẹ sa! ma sa! ti awọn ẹlomiran nwi, awa ara ilu yio tubọ ma ki nwọn lẹhin wipe Yese! mese!

"Ẹniti o fẹ baba l'ẹfẹ
Apara nla l'ẹ da
L'ẹ da, l'ẹ da, l'ẹ da
Apara nla l'ẹ da."

Ọlọla E. H. Oke, ẹniti a mọ bi ẹni mọ owo larin ilẹ yi papa ni igbati o nṣe iṣẹ ni ọgba awọn ẹlẹwọn ni ilẹ yi ki o to di Ọlọla nipa ọrọ rẹ ti o sọ ni Ajọ Igbimọ Aṣofin wipe awa ngbadun omi, odo, ina ati orun ni ilu wa nihin, awọn ti awọn si nsan owo-ori kosi anfani wọnyi ti awọn ri jẹ, nitorina awa ko si fẹ mu owo jade ni apo lati san, on wa ni atilẹhin wipe ki uwọn gba owo-ori lọwọ wa nihin, ọrọ tirẹ di ọsẹ to mbọ lagbara Soko,

Emi ni tiyin nitotọ,
KEKERE AWO.

SAMUEL ỌLATUNJI OGUNMOYERO ṢE BẸ O R'ỌRUN ALAKEJI ARE MABỌ. ỌLATUNJI ỌLATUNKU.

Ọdọm de kunrin yi jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Ologbe *Chief* Odunwo of Ondo ẹniti o ti jẹ ipe Olodumare ni *October 31, 1908*.

Ologbe si jẹ ẹniti o wa ni abo ati itọju awọn ẹgbọn rẹ lati kekere wa titi o fi pari ile Eko rẹ ko si iyọnu kankan rara.

O bẹrẹ si ṣe iṣẹ ni oṣu *Feb. 1926* labẹ Phillips *Medicine Store* gẹgẹ bi ẹniti onta ja fun wọn ni Ṣabu wọn to wa ni Ereko, aisan yi de si ni ọjọ kejidilogun oṣu *Thursday* niwọn ago mejila, awọn ẹgbọn rẹ sa ipa wọn, lẹhin na wọn tun gba *Dr.* (Oniṣegun Oyinbo) lẹhin ti iyẹn ti sa gbogbo agbara rẹ, lo wa di gbigbe lọ si *Colonial Hospital* ni *Tuesday* ọjọ kẹtalogun oṣu *August* eyiti titan rẹ de ba ni ọsan *Thursday* (25) ọjọ karundilogun oṣu *August 1927*. (Ojẹ ọmọ ọdun mẹdọgbọn).

A ki awọn ẹgbọn rẹ *Messrs.* D. O. & E. A. Ogunmoyero *of* Phillips *Medicine Store*, wọn ku ọfọ aburo wọn ọwọn, ẹniti o fi wọn silẹ lọ jẹ ipe Ọlọdumare lairo tẹlẹ ni arọ kutukutu ọjọ aiye rẹ. ...o Ọgo ni fun Oluwa.

Adura w... ni fun Iya Ologbe ki Ọlorun tọju awọn ọmọ rẹ tọ... ...iwa... Ko matun re abiku agb...

1. Arakorin ...roh n O...
Ma gbadura ... si ma ṣọra
Ọna meji wa ni 'waju rẹ
Ọkan ọna iparun, ekeji ọna si iye.

2. Ọlatunji fi wa silẹ lọ
K'a to ri erin o di igbo
K'a to ri ẹfọn o di ọdan
K'a to ri ẹiyẹ bi Okin o di gbere.

3. Arakọnrin a o pade nikẹhin
Lọdọ Ọlọrun Ẹlẹda gbogbo wa
Lati ṣe iṣiro gbogbo iwa wa
Sunre, sunre, sunre.

---

KERE O! KERE O! KERE O!

"ỌBẸ KI IMI NIKUN AGBA".

Iwe awọn ohun pataki ti o ṣẹlẹ ninu ọdun 1926 to kọja
Lati ọwọ KEKERE AWO
wa fun tita nisisiyi, o mbẹ ni Igbalẹ Iwe-irohin "Eko Akete", 24, Williams Street, Eko,
KỌBỌ MẸRIN-MẸRIN.
Afara ni ija ẹkun.

wipe ogunlọgọ ọmọlawabi ni gbogbo nkan ko lọ si dede fun mọ, ti o si jẹ wipe ẹru ti pọkọ nlpa bukata ti a ni olukuluku ngbọ ninu ile rẹ, agbara nyin tobẹ o ju bẹ lọ.

A ki nyin a ti iyawo ku ọdun ẹ ku iyedun, ki Ọlọrun Ọbangiji fi ọpọl pọ rẹ han wa Ki o ṣe ọdun yi ni rere fun wa, Ki o si jẹki ẹ gbọ ki ẹ gba nipa ofin owo-ori yi o—Amin.

## Ẹ KU ỌDUN Ẹ KU IYEDUN.

Ni iwoyi ijẹje awon ọmọ-iya wa ti a npe ni ọmọ-ẹhin Anabi Issa (Jesus Christ) nyọ ayọ ọjọ-ibi rẹ, ni iwoyi Ọla kẹ ti a ko ba ri dasi ni gbogbo wa mle loko jake-jado gbogbo agbaiye yio bọ sinu ọdun titun (1928) lẹhin ti ọdun (1927) ba ti dagbere fun wa ni agogo mejila oru oni, pe o di sa kan, ti awa na yio si daro fun pe ye! o maṣe o! o di gbere! o di arinnako! o doju ala! fun un.

## ỌDUN TITUN.

Awa ki o silẹ pe barika Mọtaba, ma wo'lẹ ma rora alafia kọ ni ẹ de bi? A si tun ni ki a bi lere silẹ pe ewo ni ẹ ri to, ewo ni ẹ ba bọ, ṣe ki iṣe ogun ọdun oni-jagidijagan tabi ọdun Alagbara lo laiye.

Ṣe o ki iṣe ọdun oni bilisi ati Aṣitani, ṣe o ki iṣe ọdun oni-jangbau ati odun oni-tẹmbẹlẹkun tabi ọdun elewu-Moto ati ti Waya oni-manamana, ṣe o ki iṣe ọdun oni-gbese ati ọdun oni-pa... tabi airoju, ṣe o ki iṣe ọdun alaisan ati ọdun iku tabi ti Ajakalẹ-arun, ṣe o ki iṣe ọdun ile jijo ọdun ole jija, ọdun ogun ati ọdun Ija'gboro?

Bi ọdun 1928 ba so wipe agbẹdo o on ko ba awọn ohun gbogbo ti a bere yi wa, ṣugbọn on wa pẹlu alafia ati irọra on wa pẹlu ayọ ati inu didun, on wa sọ mẹkunnu di olowo on wa so otoṣi di ọlọrọ, on wa sọ apọn di olobinrin on wa sọ agan di abiyamọ on wa gbe alaisan dide on wa sọ oku di aye, on wa rọjo anfani fun wa, on wa ran orun alubarika fun wa, on wa sọ ẹlẹmi kukuru di gigun, on wa sọ hilahilo ti o mbẹ fun olukuluku di ifaiyabalẹ olubori rẹ ni pe on wa tẹdi awọn alaṣeju tabi ọlọtẹ bọ'mi gbigbona, nigbana ni a to ba ṣorẹ, ṣugbọn laisi gbogbo iwọnyi nibẹ, gbogbo erokero ti ọdun 1928 ba di sikun laglara Ọlọrun ko ni iṣe—Amin.

## AWỌN ỌMỌ-ẸHIN ISSA (JESUS CHRIST.)

A ti ki olukuluku wa ku ọdun na lai da ẹnikan si, a si tọrọ adura pe ki Ọlọrun ṣọ ile ọna wa di ẹmi ṣugbọn nisisiyi a nfẹ sọrọ diẹ nipa awọn "ọmọ-ẹhin Issa Jesus Christ" gẹgẹbi ọrọ inu wosika wa ti Satide ijẹjọ.

A ni lọjọ Sunday ti awọn ọmọ-iya wa ọmọ-ẹhin Anabi Isa yio lọ jọsin ni ṣọṣi ti nwọn ba ni lati tuka adura kukuru meji ni nwọn ma nsaba ṣe, ekini ni pe mo gba Ọlọrun Baba Olodumare gbọ

Elẹda ọrun on aiye, mo gba Jesu Kiristi gbọ ọmọ Ẹnikan ṣoṣo Oluwa, Ekeji ti o je pataki ni Baba wa ti mbẹ lọrun ọwọ lọruko Rẹ ki Ijọba re de lori eyi ni a fẹ sọrọ le lori, eyiti a si fẹ lati mu ibere mẹwa yi wa.

Iwọ ọm...ẹhin Anabi Issa ti o de ṣọṣi ti o ni ilẹ ti Ọlọrun ni ki a ṣe laiye bi nwọn ti nṣe lọrun.

Ekinni:—Kini ofin mẹwa ti Mose gba ti gbogbo nyin si gba towo-tẹsẹ wipe, bọwọ fun baba on iya rẹ ki ọjọ rẹ ki o le pẹ ni ilẹ ti Oluwa Ọlọrun rẹ da ọ si iwọ ko gbọdọ va ere kere fun ara rẹ, iwọ ko gbọdọ pe orukọ Ọlọrun rẹ lasan, iwọ ko gbọdọ pania, iwọ ko gbọdọ jale iwọ ko gbọdọ ṣe panṣaga, iwọ ko gbọdọ jeri eke si ọmọ enikeji rẹ, bẹni iwọ ko gbọdọ ṣojuko-oro si aya ọmọ-ẹnikẹji rẹ, iwọ ha le tọwọ soiya wipe gbogbo ofin yi ni iwọ gba gẹgẹbi ofin Ọlọrun?

Ekeji:—Ti o ba sọ wipe gbogbo rẹ li o gba gẹgẹbi ofin Ọlọrun, o le gbogun rẹ lori pe o ni ẹnu lati sọ lọjọ ikẹhin pe iwọ ko fi orukọ Ọlọrun bura eke si ọmọ-ẹnikeji rẹ ri tabi lọwọlọwọ yi?

Ẹkẹta:—Iwọ ha le sọ wipe ẹri-ọkan rẹ ki ijẹ ọ leri pe o ti ṣe ọpọlọpọ ọmọ-ẹnikeji rẹ ni jamba?

Ẹkẹrin:—Iwọ ha le sọfun wa wipe inu rẹ o mọ si ti ẹda ẹgbẹ rẹ pe iwọ ko ni kọlọkọlọ tabi ẹri ọkan?

Ẹkarun:—Iwọ ha le sọ wipe Jesu kọ ọ lati ma jeri eke si ọmọ ẹnikeji rẹ lati ma hu'wa arankan ati iwa inunibini?

Ekẹfa:—Jesu Kiristi ha kọ ọ lati ma fi ogun ọmọ-ẹnikeji rẹ wẹlọ kakiri? Iwọ ko ha ṣe iranti iye ẹjẹ arakunrin rẹ ti o nkigbe pe ọ ni ilẹ?

Ekeje:—Anabi Issa ha fi kọ ọ lati ma pa su-su su fi aṣọ bori lalẹ lati ma le'mu aya ọmọ-ẹnikeji rẹ, lalalẹ tabi iye iwe (Letter) ti o ti fi ṣowọ si obinrin olobinrin pe ki o ... ri ọ laṣiri ni kiakia, tabi iwọ ko ha ranti ogidilẹjẹ owo ti iwọ o ba fi ṣe anfani fun aya, ọmọ ẹbi ati awọn arota rẹ ti o jẹ wipe aya ọmọ-ẹnikeji rẹ lo ng na fun?

Ẹkẹjọ:—Jesu ha fi kọ ọ wipe o tọ fun ọmọ-ẹhin on lati ma gba ijẹ lẹnu ọmọ-ẹnikeji rẹ, tabi lati ma wa iṣubu ati iparun ẹda ẹgbẹ rẹ?

Ẹkẹsan:—Tabi Jesu ha fi kọ ọ wipe ki o ma ṣe oju kokoro tabi ole si nkan ọmọ-ẹnikeji re?

Dari ẹṣẹ wa jin wa, bi a ti ndari ẹṣẹ jin ẹniti o ṣẹ wa.

Ẹkẹwa:—Iwọ ko ha mọ iye ọpọlọpọ ẹniti o ti ṣẹ ọ ti o si wa idariji wa si ọdọ rẹ ti o si fi ake kọri pe, iwọ ko ni ba oluwarẹ rẹ pọ mọ lailai ati ainipẹkun?

Anu ṣe wa diẹ lati ṣọ wipe gbogbo ofin M ati eyiti Jesu papa fi kọ awọn ọmọ ẹhin rẹ ọpọlọpọ awọn ẹniti nwọn ni awọn gba A gbo leti, a ko tun le ṣẹṣẹ sọ ti awọn ẹlomiran ti r npe ara wọn ni olukọ ani lara awọn ẹniti

wipe ọjọ mẹjọmẹjọ ni nwọn nfoju ri iwe ofin Mose ati ilana gbogbo ti Issa fi kọ wọn irufẹ awọn oni bawọnni ba ro wipe Jesu yio dari ẹṣẹ jin awọn gẹgẹbi igbagbọ awọn enia ti o nsọ wipe Jesu ti ku fun ẹṣẹ awọn o si ti lọ joko si ọwọ ọtun Baba Olodumare.

O da wa loju wipe ni iwọn igbati Jesu ti kin ofin Mose lẹhin ti on tikalararẹ si ti sọ wipe on nlọ si ọdọ Baba on, eyiyi ni pe ọgẹmọ bimọ rẹ na aimọjo ku si ọwọ rẹ, gbogbo ilana ti on fi silẹ bi ẹ ko ba tẹle oluwarẹ ti mọ wipe laisi tabitabi on yio ṣegbe.

Ki ẹnikan wa joko si kọro iyara rẹ ki o ma pitukitu ti o wu, ni ireti pe Jesu ti ku nitori ẹṣẹ gbogbo aiye ọbọlẹ ki ọ ọmọ-iya iyoku di ọjọ omiran ọjọ'rẹ, ṣugbọn ẹni a ba wifun ki o gbọ. Lẹkan si a tun ki nyin ku ọdun ẹ ku iyedun. Happy and Prosperous New Year to you all.

Emi ni tiyin nitoto,
KEKERE AWO

---

## IKU OGBO-ỌDUN

1. Yinyin igba otutu mu ni d'orunkun
Ategun igba otutu nfẹ tarẹ-tarẹ
Ẹ lu agogo Church tanu-tanu,
Ki ẹ tẹlẹ jẹ, ki ẹ rora sọrọ
Nitori ogbo ọdun nku lọ.
Ogbo ọdun, iwọ ko gbodọ ku ;
Tayọ-tayọ ni o fi tọ wa wa,
Iwo ko si fi wa silẹ lẹkan,
Ogbo-ọdun iwọ ko ni ku.

2. O dubulẹ jẹ : ko mi ara ;
Ilẹ ko ni mọ ba a.
Tirẹ tan o pari fun.
O fun mi ni ẹrẹ kun ati ifẹ toto
Ọdun titun yio si gba awọn wọnyi lọ.
Ogbo-ọdun iwọ ko gbodọ lọ
Aduru bi o ti pẹ lọ lọdọ wa to,
Bi a ti jijọ yọ pọ to
Ogbo-ọdun, iwọ ki yio lọ.

3. Akundẹnu ni ọti rẹ, o nhọ kúṣú
A ko ni ri ọdun ti o ni arinrin
Ṣugbọn bi o tilẹ jẹ pe oju rẹ di bayibayi,
Ti awọn ọta rẹ nsọrọ rẹ ni aidara
Ọrẹ mi ni iṣe,
Ogba-ọdun, iwọ ko gbodo ku ;
Awa ati irẹ ti jumọ rẹrin pọ ati jumọ sọkun pọ
Nko kọ lati ba ọ ku.
Iwọ ogbo-ọdun, bi o ba jẹ pe dandan iwọ ko ṣai ku.

4. Ẹwọ ati awada kun ẹnu rẹ,
Gbogbo ere ati awada rẹ d'opin ;
Ọmọ rẹ, arole rẹ ti ọna jinjin wa,
O nsare bi masa, ki o ba le ba a,
Ṣugbọn yio ti ku ki o to de.
Olukuluku ndu tirẹ
Ọrẹ mi, irawọ pọ lorun oni, otutu si mu,
Pẹlu ayo ati igboiya ni
Ọdun titun de wa ṣe tirẹ

5. Gbọ bi o ti nmi fikanfikan,
Mo gbọ akuko nko ni iu otutu
Mo nri firifiri bi nwọn ti nju sihin, sọhun
Ẹiyẹ nkorin : ina ko mọlẹ yan
Agogo mejila fẹrẹ lu.
Ẹ gbowo ki o to ku,
Ogbo-ọdun, a o san fun ọ
Kini iwọ fẹ ki a ṣe fun o ?
Ṣọ ki a gbọ, ki o to ku.

6. Oju rẹ yipada,
O ṣe ! ọrẹ wa lọ
Ẹ pa oju rẹ de ; ẹ fi oja gba agbọn rẹ ;
Gbogbo nyin ẹ kuro ndi oku
Ki ẹniti o da duro nikan lẹnu ọna wọle.
Ọ ẹ mi ẹsẹ titun wọle
Orẹ mi oju titun duro lẹnu ọna
Oju titun duro lẹnu ọna.

*Translated by* ADEYINKA AJAGBE-ỌSA.

---

## ATAGO K'ẸYIN APARO, OHUN OJU WA LOJU RI.

Bi o ti jẹpe awọn elomiran wa ti nwọn ko ni ero to jinlẹ dada lori titi obinrin fi ba nwọn jẹ, ni ọjọ Sunday tokọja yi ni a ri ọgbẹni kan ti nke pe ẹgba mi, ẹgba mi, nigbatii owọ ọpa Ọba tẹ awọn oniṣokoto penpe to nta ẹlẹwu ẹtu riyẹriyẹ mu toto toto Ogbẹni yi ko ti fẹ sọ pe on ṣe ohun kankan ṣugbọn nigbati paku'ẹ mu o bẹrẹ si jẹwọ pe obinrin ni on pe ni kọrọ Reclamation Road ni isọ awọn onigi ti obinrin bẹrẹ si tan on titi ọpa Ọba fi de ti obinrin na fi en fun pe ko ma mu on lọ nigbana, ara konrin ọpa lapa aṣiwere o da bi owe awọn yeruba to wipe Ọba pe onilu o jo nbo ni o ti ri owo lati pe tire, nigbati ọpa Ọba ja ja fi ọgbẹni yi silẹ o sure o fi ọwọ fa'eti.

## ỌMỌDE KI LA OYIN WO KO GBE PAMỌ SI APẸPẸ, EWỌ.

Kini fa sababi ẹgbọn pẹlu aburo to fi di ajagbila loru oganjọ a gbo pe ọmọbinrin kekere kan ti ko ju ọmọ ọdun mejila lọ ti mura tan lati sa ba ọkọ rẹ lọ, en mọ, ẹgbọn rẹ wa lọ ba pe ki lo fẹ ṣe nla ma jẹ ka gbo, ọmọbinrin kekere yi fija fun ẹgbọn rẹ pe a fi bi on ba lọ eyi tari re o, akayin fọ egungun ẹran, nigbati a wa idi rẹ titi wọn wa sọ fun wa pe awọn Ijẹbu ni o.

TẸNIMASUNWỌN.

# Kurukuru bete, Amọdun, bayi l'ẹ o ba wa Amọdun!!!

"ỌBA NKI Ọ! ALAIYE NKI Ọ!!"

"Eko Akete" ti ọsẹ to mbọ yio jẹ Akanṣe fun ohun pataki-pataki gbogbo ti o ti ṣẹlẹ l'Eko ati ẹbin ẹkun lọdun ti a ṣẹṣẹ ngbe sin yi, eyiti ko yẹ ki ẹnikẹni gbagbe bọrọ. A o si sọrọ nipasẹ Ọgbẹni Herbert Macaulay ti yio jẹ imọlẹ fun ẹnikẹni ati ọta ati ọrẹ rẹ

Sisi (6d) ni tita Akanṣe "Eko Akete" yi, ẹ tete wa sanwo silẹ lati ọtunla (Monday) ni 24, Williams St. Eko.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH.

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq., *The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.* *N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE. "Shake the Bottle."

### AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Sugbon nigba pupo ni o nje pe ara okunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupo fun Are, Eda ati gbogbo arun ti ki e ki okunrin se abiamo.

*N.B.*—O ye ki gbogbo okunrin ma lo igo meji-meji lososu—Ise ti egbogi na nse ni ara ko se royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Paintull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq. 41, Offin Road, Lagos.

*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONISE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun Al oyun, Iju, Eda, Aran, Oyun ti o ba fe baje, ati orisirisi arun mi ti o je ki obinrin bimo.

PRICE 10/- PER BOTTLE.

Postage 2/6 extra.

## WHITE'S WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq. 41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle Packing and Postage 2/6 extra. Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISOYE.

Egbogi yi dara pupo fun awon omo-ile-iwe, awon ti o nfi iwe sise ati gbogbo awon ti o ba ni lati lo fun idanwo.

*Iba se ompde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer.

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*

The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA EJE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun obinrin ti ko ba ri nkan osu re mo (Islai to asiko), nkan obinrin ti ko ba po to. Ase Ewure pipoju, Eda ti o ba gbo, Eyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Esanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE,
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

**A Trial is Solicited.**

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

**TO LET.**

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

**A. B. Williams,**
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmin ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ oriṣiriṣi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to koj si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ loriṣiriṣi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fu ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.